# Mún kí ààbò wà ní Wales nígbà òtútú yìí

DIOGELU CYMRU
KEEP WALES SAFE

Llywodraeth Cymru
Welsh Government

## Àlàyè kòkòrò kòrónà tó ṣe kókó

Gbogbo wa nílò láti mún ìdádúró bá ìtànkálẹ̀ Kòkòrò kòrónà ní Wales.

## Bí o se lè dáàbò bo ara rẹ àti ẹbí rẹ

### FỌ ỌWỌ́ DÉÉDÉÉ

Pàápàá bí o bá lọ rajà, lọ gba ǹkan tàbí o fẹ́ fọwọ́ ba ounjẹ

### SE GÀÀYÀ LÁWÙJỌ

Dúró ní ìwọ̀n ẹsẹ̀ bàtà méjì kúrò lọ́dọ̀ àwọn ẹlòmíràn tí kìí se mọ̀lẹ́bí rẹ.

### WỌ ÌBÒMÚN

Níbi tó yẹ.

### MỌ ÀWỌN ÀPẸRẸ

Àwọn apẹrẹ kòkòrò kòrónà gbòógì ni ara gbígbóná, ikọ́ léraléra, tàbí àyípadà ìtọ́wò tàbí ìgbóòórùn

### ÌYARA ẸNI SỌ́TỌ̀

Dúró sílé bí ìwọ tàbí ènìyàn kan nílé rẹ bání àwọn àpẹrẹ, tàbí bí àwọn tó ń tọ pinpin ìfarakínra bá wí bẹ́ẹ̀

### LỌ SE ÀYẸ̀WÒ

**Pe 119** tàbí **bèèrè fún àyẹ̀wò orí ìtàkùn ayélujára** lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ tí o bá ti rí ọ̀kankan nínú àwọn àpẹrẹ – kódà bó bá jẹ́ kékeré.

### ṢÈRÀNWỌ́ FÁWỌN TÓ Ń TỌ PINPIN ÌFARAKÍNRA

Àwọn tó ń tọ pinpin ìfarakínra yíò pè láti fún ọ lámọ̀ràn lórí ohun tí o ní láti ṣe bí o bá ti ní ìfarakínra pẹ́kípẹ́kí pẹ̀lú ẹni tí àwọn àyẹ̀wò ti sàfimúnlẹ̀ pé ó ní kòkòrò kòrónà. Ẹrọ ìbáraẹnisọ̀rọ̀ yìí **02921 961133** nìkan ni wọ́n lè fi pè ọ́.

### GBA ÁÀPÙ ÌLÉEṢẸ́ NHS LÓRÍ COVID-19

Ó jẹ́ ọ̀nà tó yá láti mọ̀ bóyá ò ń fojú wínná à ti ní Kòkòrò kòrónà. Ṣe àgbàsílẹ̀ rẹ̀ láti App Store tàbí Google Play.

### MÚN ÀDÍNKÙ BÁ ÌFARAKÍNRA RẸ PẸ̀LÚ ÀWỌN ÈNÌYÀN MÍRÀN

Ronú dáradára lórí ibi tí o lọ àti ẹni tí o pádé. Bí ibi tí o lọ sàbẹ̀wò sí bá se pọ̀sí àti báwọn ènìyàn tí o pàdé bá se tó, pàápàá jùlọ nínú ilé, bẹ́ẹ̀ náà ni ó se se é ṣe láti ní kòkòrò kòrónà kí o sì tún kó o ran àwọn ẹlòmíràn.

### ÌGBÁYÉGBÁDÙN RẸ

À ń gbé ní àkókò líle. Ó ti se pàtàkì báyìí láti bójútó ọpọlọ àti Ìgbáyégbádùn rẹ báyìí Wàá rí àmọ̀ràn ọ̀fẹ́ àti ìrànwọ́ gbà bí o bá lọ sí **www.callhelpline.org.uk**, tàbí bí o bá pe **0800 132 737** o sì le fi àtẹ̀jíṣẹ́: **ÌRÀNLỌ́WỌ́** ṣọwọ́ sí **81066**.

### ILÉEṢẸ́ NHS ṢÌ WÀ NÍBÍ FÚN Ọ — RÀNWǍ LỌ́WỌ́ LÁTI LÈ RÀN Ọ́ LỌ́WỌ́

Ọnà tí ò ń gbà lo àwọn ìpèsè ìṣẹ NHS lè yàtọ̀ lákòókò òtútù yìí ṣùgbọ́n ó sì wà nílẹ̀ fún nígbà tí o bá nílò rẹ. Ṣèrànwọ́ fún iléesẹ NHS nípa pípa àjọṣọ mọ́, àti lílo ìlànà tó yẹ fún àìsàn àti ọgbẹ́.

Bí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ ṣùgbọ́n tí kì í se pàjáwìrì, lọ sí **https://111.wales.nhs.uk**. Tàbí kí o pe **111** Fún àmọ̀ràn tàbí kí o kàn sí GP, tàbí olóògùn, olùtọ́jú ojú tàbí olùtọ́jú ryín.

**Fún àlàyé bó se ń jáde àti àmọ̀ràn lórí Kòkòró kòrónà ní Wales, jọ̀wọ́ ṣàyẹ̀wò sí ìtàkùn ìjọba ilẹ̀ Wales lórí**

**www.gov.wales/coronavirus**

Ìwé ìléwọ́ pélébé yìí wànílẹ̀ láti lo bí wọ́n bá béèrè:
customerhelp@gov.wales 0300 0604400

OGL © Crown copyright 2020, Ìjọba ilẹ̀ Wales WG41349

Llywodraeth Cymru
Welsh Government

## Àtẹ̀jíṣẹ́ láti ọ̀dọ̀ olóòtú Wales àkọ́kọ́

Ọdún 2020 jẹ̀ ọdún tó gùn tó sì le koko fún gbogbo wa. Kòkòrò kòrónà ti mú ìbòjú gígùn sí ayé gbogbo wa, sìbẹ̀ kò tí ì sí òpín nítòsí sí àjàkálẹ̀ ààrùn apanirun yìí.

Bí gbogbo wa bá gbárapọ̀, a lè, a ó sì mún àyípadà wá sí ọ̀nà tí kòkòrò yìí yíó gbà lọ.

A késí gbogbo ènìyàn lọ́dún yìí láti se àwọn ohun àràmàdà àti ìfàyàrán tó yàtọ̀ láti lè mún kí gbogbo wa wà ní àlááfíà.

Mo ń bèèrè pé kí o tẹ̀síwájú nípa síse gbogbo àwọn wọ̀nyí.

Kòkòrò yìí ma ń gbilẹ̀ pẹ̀lú ìfarakínra. Bí a bá fẹ́ pinwọ́ kòkòrò , à nílò láti mún àdínkù bá àwọn tó ń ní.

À ń fojú winná ewu títan tàbí níní kòkòrò ńgbàkúgbà tí a bá ń pádé ènìyàn kan.

Níbí ọdún Kérésìmesì se ń sùmọ́, jọ̀wọ́ ronú dáadáa lórí ibi tí ò ń lọ, ohun tí ò ń se àti ẹni tí ò ń ri.

Èyí yíò dáàbò bo ọ́, àwọn ẹbí rẹ àti àwọn ọ̀rẹ́.

**Pẹ̀lú àjọsepọ̀ ni a fi le dáàbò bo Wales.**

O seun



Mark Drakeford MS,
Olóòtú Àkọ́kọ́ Wales